# Àkókò àjọlò papọ̀

## Àwọn iṣẹ́ ṣíṣe oní fàájì àti ìrọ̀rùn láti ṣe pẹ̀lú ọmọ rẹ kékeré ní ilé

National Literacy Trust
Change your story

# Ẹ káàbọ̀

**Bíbá ọmọ-ìkókó tabi ọmọ rẹ kékeré sọ̀rọ̀ ati kíkàwèé pọ̀ pẹlu wọn máa n fún wọn ní ìbẹ̀rẹ̀ ìgbé-ayé tó dára jùlọ**

O ní ipa àrà-ọ̀tọ̀ kan áti kó gẹgẹ bi òbí Iroyin ayọ ibẹ̀ ni pé o kò nilo lati jẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ kí o tó lè ṣèrànwọ́ fún ọmọ rẹ lati kọ́ ọ lẹ́kọ̀ọ́.



**Njẹ́ ìwọ mọ̀** pé àwọn ọmọdé máa n kẹ́kọ̀ọ́ pupọ lára rẹ nipaṣẹ awọn ìrírí kéékèèké ojoojumọ bí!



**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Àwọn olobó oníràwọ̀ tí n bẹ ninu ìwé yìí n fúnni ní àwọn àmọ̀ràn nla lori bí o se lè ṣatilẹyin fún ẹ̀kọ́ ọmọ rẹ, kí o sì mú wọn wà ní ìgbaradì fun ilé-ẹ̀kọ́.

**Àwọn iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Lò àwọn iṣẹ́ ṣíṣe Wọrds of Life lati ṣèrànwọ́ fún ọmọ rẹ láti kọ́ èdè tí wọn yoo maa sọ ní ilé-ẹ̀kọ́.

Gbìyànjú awọn yìí fún ìbẹ̀rẹ̀. O lè rí àwọn àmọ̀ràn sií lori ayélujára ní **wordsforlife.org.uk.**

**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Inú ọmọ rẹ yóò dùn gan an nigba tí ìwọ bá sọ fún pé 'o káre'! Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rọ̀-ìwúrí yoo mú ara ọmọ rẹ yá-gágá nípa ararẹ̀.

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Ba ọmọ rẹ tàkurọ̀sọ nígbà tí o bá lè wà ní ìta àti ìgbà tí o bá wà ní àyíká – tí ẹ bá nrìn lọ loju ọna, nínu ọkọ̀ èrò, ní ibikíbi! Wọn lè kọ ọpọlọpọ ọ̀rọ̀ tuntun lati ẹnu rẹ.

# Tàkurọ̀sọ, Ṣeré, Kàwé

**Ìtàkurọ̀sọ ṣe kókó!**

Bá ọmọ rẹ sọ̀rọ̀, jẹ́kí òun naa sọ̀; tẹ́tí sí ọmọ rẹ, jẹ́kí òun naa tẹ́tí sí ọ pẹlu.

Awọn ọmọdé maa nkẹkọọ nípasẹ̀ bíbéèrè ìbéèrè, sísọ̀rọ̀ nípa àwọn èrò inu wọn, ṣíṣe apejuwe awọn ohun tí wọn n rí àti àwọn èyí tó n yà wọn lẹnu.

Nigba ti o bá n sọrọ pẹlu ọmọ rẹ, fàájì ló jẹ́ fún yin papọ̀. Gbìyànjú láti:

- Bèèrè ìbéèrè
- Síso fún wọn nipa awọn ìrírí ojoojumọ
- Ṣíṣe àwàdà
- Dídá àpárá
- Tita àyò pọ̀
- Kíkọ orin




**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Fún àmọ̀ràn siwaju si i, ṣe àbẹ̀wò sí **wordsforlife.org.uk**

**Njẹ́ ìwọ mọ̀** pé bí ó bá ṣe n sọrọ pẹlu ọmọ rẹ tó ati bí wọn bá ṣe n rí i tí o n lò awọn ọrọ pupọ tó, bẹẹ ni o ṣe n mú wọn pegedé tó ní ọmọ-ọdun mẹwaa (10) ní ilé-ẹ̀kọ́?

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Ṣọ̀rọ̀ pẹlu ọmọ rẹ nípa àwọn ohun tí o maa n ṣe ninu akitiyan ojoojumọ rẹ, bi i fífọ abọ́ tabi dídáná ounjẹ alẹ́

# Ṣeré

Òye ohun tó n lọ layikaa maa n yé awọn ọmọdé nípasẹ̀ eré ṣíṣe wọn!

Eré ṣíṣe ṣe pataki pupọ fun ìdàgbàsókè awọn ọmọdé. Bíbá àwọn ọmọdé míràn ṣeré pọ̀ n ṣeranwọ fún wọn fún ìbáraẹnisọ̀rọ̀, ṣíṣe nnknan ní tẹ̀lé-n-tẹ̀lé, pípín nnkan laarin araẹni ati ṣíṣe ọ̀rẹ́.

Àwọn ọmọdé maa n gbadun títẹ̀lé èrò tó sọ sí wọn lọ́kàn lati sọ oriṣiriṣi nnkan di ohun-èlò ìṣeré wọn. O lè pese awọn ohun ìmúra bí i bàtà agbalagba, aṣọ, apamọwọ, tabi páálí ọ̀fifo paapaa – àwọn àpótí nlá yoo dara pupọ!



**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Tí ariwo eré ṣiṣe bá ti n pọ̀jù, ẹ kọrísí pápá ìṣeré agbegbe yin!

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Ṣe alábàápín ìtàn náà*We're Going On A Bear Hunt*' lẹyin naa sì wá tẹ̀ síwájú sí ọgbà tàbí ibi ìgbafẹ́ agbegbe yin bí eni pé ẹ fẹ lọ ṣe ọdẹ looto!

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Darapọ, kí o sì di ọ̀ṣeré lasiko tí awọn ọmọ rẹ bá nṣere tó sọ sí wọn lọ́kàn! Beere ibeere lori ìwà-ọmọluwabi lọwọ wọn tabi kí o ṣapejuwe awọn ohun tí o nṣe fun wọn. Eyi lè fún ọmọ rẹ ní anfaani lati gbọ awọn ọrọ tuntun, kí o sì lè yanju awọn ìṣòro kan.

**Njẹ́ ìwọ mọ̀** pé gbígba ọmọ rẹ láàyè lati yàn ohun ìṣeré n ṣe agbátẹ̀rù fún òmìnira rẹ, tí ó sì tún ṣeranwọ fún un lati gbaradì fùn ilé-ẹ̀kọ?



# Kíka àwọn àkọlé

**Àkọjáde n bẹ níbi gbogbo!**

Awọn ọmọde ngbé nínú ayé tó kún fún àkọjáde, tí wọn sì n rí awọn àtẹ̀jíṣẹ́, awọn aworan ati awọn àlẹ̀mọ́ níbi gbogbo.

Didá ilé-ounjẹ tabi orukọ ile-itaja tó jẹ́ ààyò wọn mọ̀ jẹ́ awọn igbesẹ akọkọ sí kíkọ́ kíkàwé ati kikọwe.

**Njẹ́ o mọ̀** pé bí ọmọ rẹ bà ṣe n rí ọ tí o nkawe tó, bẹẹ naa ni òun naa yoo ṣe maa nifẹẹ lati kàwé pẹlu!

**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Rí daju pé ọmọ rẹ n rí ọ pé o n kà awọn iwe tí o gbadun, bí i awọn ìwé, iwe-iroyin àtìgbàdégbà, àwọ̀rẹ́rìn ín, iwe-dídáná ounjẹ tabi awọn itọnisọna, kí o sì sọ idi tí o fi n ṣe bẹẹ fun wọn

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Nigbakigba tí o bá n jade kiri pẹlu ọmọ rẹ, maa wo awọn àkọlé, àmì, àlẹ̀mọ́ ati ọrọ gbogbo layiika rẹ Fún wọn ní ìwúrí kí wọn maa fi awọn tí wọ dámọ̀ hàn ọ, kí o sì maa ran wọn lọwọ lati 'kà' wọn!

# Jẹun, sùn, gbéra

**Fi ounjẹ bọ awọn ọmọdé bí wọn ṣe n dàgbà**

Ounjẹ àdàlù, olóríṣiríṣi pẹlu èṣo tùtù, ewébẹ̀ ati awọn eroja ara maalu ṣe pataki fun ṣíṣèrànwọ́ fún idagbasoke ara ati egungun inu ilera. Dídáná ounjẹ lati ìbẹ̀rẹ̀ kò nání lówó bí i kí a maa rà ounjẹ tí wọn ti ṣè sílẹ lọ. Àwọn ounjẹ gbígbẹ ati ti inu agolo bí i pasta, tomati ati ẹ̀wà jẹ́ awọn ounjẹ-ojoojumọ ori pẹpẹ tó dára, tí owó wọn kò pọ̀, tí a lè fi wọn pèsè oniruuru ounjẹ miran.




**Njẹ́ o mọ̀** pé ọpọplọpọ awọn ile-itaja ló ní awọn iwe-ìdáná ounjẹ tí owó wọn kò gara rara? Tàbí, ẹ lè wo orí ayélujára fún àwọn ìmọ̀ràn míràn: **nhs.uk/start-for-life/baby/recipes-and-meal-ideas**

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Jẹki ọmọ rẹ kópa nigba tí o bá n dáná ounjẹ nipa síṣọ awọn ohun tì o n ṣe fún wọn

**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Beere lọwọ awọn ọ̀rẹ iru ohun tí awọn ọmọ wọn fẹran lati maa jẹ kí ẹ sì ṣe pasipaarọ awọn iwe-dídáná ounjẹ!

**Top tip**

Beere nipa ẹgbẹ olounjẹ aarọ ati ọ̀sán tí o lè wù ọ lọwọ ile-ẹkọ ọmọ rẹ!

# Sùn daadaa

**Sinmi, baralẹ!**

Sísùn ati sísinmi daadaa nigbagbogbo ṣe pataki fún awọn ọmọdé bí wọn ṣe n ga, tí wọn sì n dagbasoke.

**Awọn ìlànà ní àṣáálẹ́**

Awọn ìlànà ní àṣáálẹ́ lọ bayii:

- Agogo 6.45 alẹ́: wọ pijamasi, fọ ẹnu, lọ si ilé-ìyàgbẹ́.
- Agogo 7.15 alẹ́: àkókò ìdákẹ́jẹ́ẹ́ pẹlu iwe kan, pípa ìtàn tabi sísọ̀rọ̀ kẹlẹkẹlẹ.
- Agogo 7.30 alẹ́: ká sùn láyọ̀, kí a sì paná[1]

**Njẹ́ o mọ̀** pé awọn orin amọ́kànbalẹ̀ ati orin tútù lè mu ara awọn ọmọdé balẹ̀ kí wọn sì lè sùn wọra bí?



**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Gbiyanju lati dín 'àkókò ìwòran kù lori mohunmaworan tabi kọmputa ní awọn ìgbà tó ṣaaju kì oorun tó tó sùn, toripe ó lè dènà kí awọn ọmọ ma fẹ́ sùn.

Fún awọn àmọ̀ràn lati ṣeranwọ fun ọ nipa oorun awọn ọmọ, lọ sí **sleepfoundation.org**

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Dípò ki o kàwé kan ní àṣáálẹ́, gbiyanju kí o ronú ìtàn kan tó sọ sí ọ lọ́kàn.



# Ó yá gbéra

## Asiko tó lati gbọn ara nù

Ìwádìí ti sọ pé awọn ọmọdé tí ọjọ́-orí wọn tó ọdun marun un ní bí i wakati mẹta fun àkókò idaraya tó pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ kaakiri ọjọ kan[2]. Èyí tí rírìn, fífò, sísáré, gígòkè ati fífa-tẹ̀ẹ̀tẹ́ wà ninu rẹ̀. Ara awọn ọmọdé n ga, ó sì n dagbasoke kánmọ́kánmọ́ ní àkókò yii. Ara àwọn ọmọdé a maaa yá gágá, wọn sì nilo lati maa gbera sọ lati wà ní ilera ati ara yíya.

### Àwọn olobó oníràwọ̀

Wá ìdaraya kan tí o ma n gbadun lati ṣe (boya ijó jíjó sí orin tabi sísáré-jẹ́jẹ́), kí o sì gba awọn ọmọ rẹ niyanju kí ọn darapọ mọ́ ọ!

### Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life

Beere lọwọ ọmọ rẹ kí ó sọ irú eré kan tí wọn maa nṣe ni kilaasi awọn èwe. Beere ohun tí wọn fẹ́ tabi eyi tí wọn kò fẹ́ - ati ìdí rẹ̀.

**Lára àwọn gbápá-gbẹ́sẹ̀ tó dara jù fún awọn ọmọdé tí wọn lè rìn fúnra arawọn ni yii:**

- Erépá (bíi bojúbojú tabi ẹsẹ̀ tí ó há sínú ẹrẹ̀)
- Sísáré kiri
- Fifò lori tirampolini
- Gíun kẹ̀kẹ́
- Ijó jíjó
- Lílúwẹ̀ẹ́
- Okùn fífò
- Jimnasitiki[3]

# Kíni o lè ṣe lati ṣatilẹyin fún ọmọ rẹ

Ìwádìí fihàn pé awọn nnkan meje kan nbẹ ti awọn òbí lè ṣe pẹlu awọn ọmọ wọn lati ran wọn lọwọ nipa kíkẹ́kọ̀ọ́ lati ṣe àṣeyege láyé[4].

### Ẹ jọ kàwé, kí ẹ tún jọ pa ìtàn

Jíjọ maa wo awọn ìwé papọ̀ jẹ́ ọna kan tó dara jù lati kẹkọọ  lati ìgbà èwe.

### Bọ́ síta, lọ kiri

Ẹ rìn jade tabi kí ẹ jọ lọ sí ilé-ìtajà, yoo fun ìwọ ati ọmọ rẹ ní awọn ìrírí tuntun, ninu eyi tí a ti rí wíwòran níní ìmọ̀lára, gbígbọ́ òórùn, ṣíṣe ìtọ́wò ati gbígbọ́ ọrọ ati pẹlu ọpọ títàkurọ̀ṣọ!

### Kọ orin àti àkọ́sórí

Kíkọ àkọ́sórí ati orin fún awọn èwe maa n ṣeranwọ fun ọmọ rẹ lati kọ awọn ìró àti ọ̀rọ̀ tuntun nipasẹ àkọ́sórí ati kíkọ orin ní ọpọ ìgbà.

### Níni anfaani sí awọn ìwé

Tí gbọ̀ngàn-iwé agbegbe yin bá sí, o lè yá ìwé ọ̀fẹ́, kí o sì kópa ninu awọn ìdárayá fún awọn ọmọdé. Awọn ilé-ẹ̀kọ́ àwọn èwe, gbàgede ati ilé-ẹ̀kọ́ awọn ọmọdé lè pese anfaani sí awọn ìwé ọ̀fẹ́. Ìwọ ṣa bèèrè!

### Ẹ ṣeré papọ̀

Awọn ọmọdé a maa kẹkọọ bí wọn bá ti n ṣeré. Ṣíṣeré papọ̀ maa n ran awọn ọmọdé lọwọ lati mú kí ìjáfáfá tí wọn nilo nipa bíbánisọ̀rọ̀ ati bíbánisẹpọ̀ gberu sí i.

### Kùn ọ̀dà, yà àwòrán

Yíya àmì àti kíkọ ohunkóhun jẹ́ ibẹ̀rẹ̀ kíkọ́ bí a ṣe nkọ̀wé.

### Fi awọn Alufabẹẹti ṣeré

Ṣíṣeré pẹ̀lú awọn àrà ati pípè awọn lẹta alufabẹẹti maa n sọ ẹ̀kọ́ di fàájì.

**Awọn idaraya keekeeke yii maa n mú ìyàtọ̀ bá bí ọmọ rẹ ṣe n kẹkọọ tí ó sì n dagbasoke ninu fifetí-sílẹ̀, sísọ̀rọ̀, kíkàwé ati kíkọ̀wé. Ẹ lè jọ gbadun arayin papọ, kí ẹ sì maa gbaradi fun ilé-ẹ̀kọ́ nigba kannaa!**


I took part in
Bookstart Corner



# Ẹ máa pìtàn

O kò nilo lati ka awọn ọrọ naa nigba gbogbo. Wíwo àti ṣíṣe àlàyé awọn ìwé aláwòrán jẹ́ ọna pataki kan lati ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ lati maa gbádùn ìtàn. Tí ẹ bá n sọ èdè miran nílé, ẹ maa sọ ìtàn nipa awọn aworan yii ní èdè yin.

Tí ẹ bá n pín awọn ìwé kà laarin ara yin, ó maa jẹ́ fàájí fún yin papọ ni.

- Ẹ sọ nipa ohun ti n bẹ lẹ́yìn páálí ìwé naa, kí ẹ sì tọka sí àkọ́lé rẹ̀.
- Jẹki ọmọ rẹ mú ìwé naa lọwọ, kí ó sì máa ṣí awọn ojú-ewé rẹ̀.
- Gbá wọn níyànjú lati sọrọ nipa awọn aworan naa.
- Lò ohùn oriṣiriṣi fun awọn olùṣe inú awọn aworan naa. Fi ohùn dábírà fun awọn nnkan bí i omi tó fọ́n síni lára, ọkọ̀ tó n fọn fèrè tabi dídún awọn ẹranko.
- Nigba ti ìtàn naa ba tán, o lè beere lọwọ wọn pé ṣe wọn gbadun rẹ̀ àti pé njẹ wọn ní olùṣe kan tó jẹ́ ààyò wọn.

**Njẹ o mọ̀** pé awọn ọmọdé tí àwọn òbí wọn maa n kawe sí leti nigbogbo ìgbà lákòókò tí wọn wà ní ọmọ-ọdun marun un maa n ṣe daadaa ninu ìdánwò ìṣirò ati sípẹ́lì tí wọn bá ti di ọmọ-ọdún mẹrindinlogun (16) ju awọn tí wọn kò ṣe irú iranwọ bẹẹ fun?[5]

**Njẹ́ o mọ̀** pé awọn ọmọdé maa nsaaba ní ààyò ìtàn kan tí wọn maa n fẹ́ gbọ́ laimọye ìgbà bí? Eyi maa nràn wọn lọwọ lati mọ̀ nipa ààtò ọrọ, tí wọn sì n lè so ọrọ naa mọ́ ìtàn naa – eyi tí í ṣe awọn igbesẹ àkọ́kọ́ ninu kíkàwé!

**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Ẹ dìjọ kọ́ ihò-ẹranko (ẹ da aṣọ bò tabili), pẹlu àyè tí ẹyin mejeeji maa jọ wà. O lè kọ́ ihò-ẹranko tìrẹ lati inu ìtàn naa – ó lè jẹ́ ihò iwin, ọkọ̀ rọkẹẹti, tabi ọ̀wọ́n ọmọ-ọbabinrin kan.

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Ba ọmọ rẹ sọrọ nipa awọn ohun tí o ṣe nigba ti ìwọ naa wà ní ọmọdé. Jẹki gbogbo ẹbí kópa – awọn òbí-àgbà pẹlu lè fẹ́ pa awọn ìtàn lati akoko tí awọn naa n dagba!

# Kọ orin àti àkọ́sórí

Orin ati akọsori maa n mú ìpèdè, ìgbápágbẹ́sẹ̀ awọn ọmọdé gbèrú sí i, tí wọn bá ní awọn ìṣe kan ninu. Awọn míràn pẹlu maa n ṣeranwọ lati mọ̀ òǹkà.

Má mikàn bí ohùn rẹ kò bá tilẹ̀ dùn fun orin kíkọ, kò ṣe nnkankan, àti pé bí o bá ṣe n túbọ̀ kọrin pẹlu ọmọ rẹ ni igboya rẹ naa yoo ṣe maa ga sí.

Tì o kò bá mọ ohùn orin náà, lọ yá àwo CD awọn àkọ́sórí naa lati gbọ̀ngàn ìkàwé tabi kí o wò wọn lori YouTube. O tilẹ̀ lè ṣe orin tìrẹ gan an fúnraàrẹ, tabi kí ẹ jọ kúkú maa kọrin tẹle redio papọ̀.



**Nję o mọ̀** awọn orin ati àkọ́sórí tilẹ̀ lè ṣeranwọ lati kọ ọmọ rẹ nipa àgbáyé bí? O lè ṣe dídún awọn ẹranko tí n bẹ ninu orin "Old MacDonald Had A Farm" kí o sì ka òǹkà 1, 2, 3, 4, 5 tí n bẹ́ ninu "Once I Caught A Fish Alive"!

**wordsforlife.org.uk/themes/songs-and-rhymes**



# Orin "Incy Wincy Spider"


Ṣe bí òṣeré fun awọn nnkan tí orin naa n sọ bi ẹ ti nkọrin naa, tabi kí o ṣe aláǹtakùn àti ọ̀pá-omi tìrẹ nipa lílo awọn kòkò yógọ́ọ̀tì, òwú ati awọn àgbà bébà-ìnuwọ́ lati inu ilé-ìdáná. O lè rí fídíò orin naa kan pẹlu àwọn ìgbésẹ̀: **wordsforlife.org.uk/activities/incy-wincy-spider**

*Incy Wincy Spider climbed up the water spout*

*Down came the rain and washed the spider out*

*Out came the sunshine and dried up all the rain*

*Incy Wincy Spider climbed up the water spout.*



**Àwọn olobó oníràwọ̀**
Tí o bá awọn orin ati àkọ́sórí míran ní awọn èdè míràn, kọrin naa pẹlu ọmọ rẹ.

# Ẹ ṣeré papọ̀

Kíkọ́ bí a ṣe n pín nnkan, ṣe nnkan ní tẹ̀léntẹ̀lé, bánisọ̀rọ̀, wà ní ìbalẹ̀ara, àti ṣíṣe ọ̀rẹ́ pẹlu awọn míràn jẹ́ àwọn ìṣe tí eniyan nílò fún igbe-aye ṣugbọn tí ó maa n gba asiko lati kọ awọn ìṣe yii! O lè ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọmọ rẹ láti gbáradì fún kíkọ́ àwọn ẹ̀kọ́ pàtàkì yìí nípa ṣíṣe eré papọ̀, tàbí ṣíṣe àgbékalẹ̀ àwọn déètì ìṣeré pẹ̀lú àwọn ọ̀rẹ́ tàbí àwọn mọ̀lẹ́bí, yálà ní ojúkoojú tàbí nípasẹ̀ Face Time tàbí WhatsApp.



**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Gbogbo ọmọdé ló yàtọ̀! Ara àwọn kan yá gágá wọ́n sì ní ìgbóyà ju àwọn míràn lọ -- máse ṣe àfiwé kí o má sì ṣe fòyà – ìwọ ni o mọ ọmọ rẹ jùlọ nítorí náà fún u ní àtìlẹ́yìn àti ìwúrí tí ó nílò.

**Njẹ́ o mọ̀** pé kíkọ́ bí a ti nbá àwọn ẹlòmíràn ṣeré ṣe pàtàkì fún ìdàgbàsókè ti ara, ti àwùjọ àti ti ìrònú àwọn ọmọdé? O lè jẹ́ olùbániṣeré gidi fún ọmọ rẹ.

Sá fi ọkàn bá àwọn ohun tí ó nífẹ̀ẹ́ sí lọ!




**Àwọn ọmọdé nṣeré ní onírúurú ọ̀nà tó pọ̀:**

- Ṣíṣeré fúnra wọn
- Wíwo bí àwọn ọmọdé míràn tí nṣeré
- Bá àwọn ẹlòmíràn ṣeré; ní ṣíṣe àwọn iṣẹ́ kan náà ṣùgbọ́n láì máa so pọ̀ mọ́ ara wọn
- Fífi ìfẹ́ hàn sí eré tí àwọn míràn nṣe kí wọ́n si bẹ̀rẹ̀ sí í bá ara wọn sọ̀rọ̀
- Bíbá ara wọn ṣeré, ní ọ̀pọ̀ ìgbà ní ìsọ̀rí kéréje

**Àwọn olobó oníràwọ̀**
Ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ kí o sì fún u ní ìdánilójú láti gbé ìgbóyà rẹ ró bí ó ti bẹ̀rẹ̀ síí ní àwọn ọ̀rẹ́  tirẹ̀.

# Fi awọn lẹta àti nọmba ṣeré

Onírúurú eré ni ó wà tí o lè fi àwọn lẹta àti nọmba ṣe, láti ara ìrí àti ohùn wọn títí dé kíkọ́ àwọn ọ̀rọ̀ tuntun tí wọ́n jọ ní lẹta ìbẹ̀rẹ̀ kan náà. O lè wá nọmba tí ọmọ rẹ lè dámọ̀, bíi nọmba ara ilẹ̀kùn rẹ tàbí ọjọ́ orí wọn, kí o sì ríi bóyá o lè rí àwọn nọmba yìí lórí àwọn ọkọ̀ nlá, ilé ìtajà tàbí àmì ojú ọ̀nà. Rántí pé àwọn lẹta àti nọmba n bẹ kaakiri!



**Àwọn olobó oníràwọ̀**
Ka ònkà sókè pẹ̀lú ọmọ rẹ – wo iye àwọn ìgbésẹ̀ tí o nílò láti dé ibi ilẹ̀kùn iwajú ilé rẹ tàbí iye òpó iná tí tí o là kọjá bí o ti nlọ sí ibi ìgbafẹ́!

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**
Sọ̀rọ̀ nípa àwọn lẹta tí o lè rí nínú àfiránṣẹ́ àti ìwé-iroyin àtìgbàdégbà àtijọ́. Gé àwọn kan lára lẹta àwọn lẹta náà kí o sì ṣe àwòrán aláṣàpọ̀. Wò bóyá o lè rí lẹta àkọ́kọ́ orúkọ ọmọ rẹ. Tí kò bá tíì dá lẹta náà mọ̀ síbẹ̀, ya àwòrán rẹ̀ papọ̀ kí o sì ríi  bóyá o lè ríi nígbà tí o bá jáde tí o sì nrìn káàkiri

## *‘Mo nlọ ọgbà ìgbafẹ́’*

Ẹ jọ ṣe eré kan nípa ṣíṣe é ní àṣegbà kí o sọ ohun tí ìwọ yóò mú nígbà tí o bá nlọ sí ìrìnàjò sí ọgbà ìgbafẹ́. Ìlànà náà ni pé o lè mú àwọn nnkan tí ó ní ohùn ‘p’ nìkan (fún àpẹẹrẹ, ‘Mo nlọ sí ọgbà ìgbafẹ́, mo sì maa mú ounjẹ/ayékòótọ́/lẹẹdi ìkọ̀wé kan’). O lè jẹ ìgbádùn sís nípa ṣíṣe àyípadà ibi tí o nlọ (fún àpẹẹrẹ, sí etí òkun, níbi tí o ti lè mú àwọn ohun tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ‘s’). Njẹ́ o lè rántí ohun gbogbo tí ìwọ yóò mú lọwọ?

## Plastisiini tàbí àwọn ìṣù lẹta fún ìṣeré

Ẹ gbiyanju kí ẹ jọ fi plastisiini ṣe àwọn àrà lẹta papọ̀, tàbí kí ẹ ṣe ìṣù lẹ́tà fún ìṣeré tiyin.

Ẹ ṣe àwọn àpòpọ̀ yii:

- ife ìyẹ̀fun-burẹdi lásán méjì
- ìdajì ife omi tútù
- ṣíbí òróró ìjẹun méta
- ṣíbí omi ọsàn wẹ́wẹ́ kan (kì í ṣe dandan)
- ohun tó n fún ounjẹ láwọ̀ tàbí mú ounjẹ dán tó wù ọ́.

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Láti ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ láti lè tètè mọ ìwé kíkà, lo àwọn ohùn lẹta dípò àwọn orúkọ lẹta alfabẹẹti. Lílo àwọn ohùn lẹta nígbà tí ẹ bá jọ nṣe àwọn eré bíi ‘mo nlọ síbi ìgbafẹ́’ tàbí ‘mo ṣe amí’, yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ fún u láti pe àwọn ọ̀rọ̀ jáde bí ó ti nkọ́ bí a ti nkàwé.





# Bọ́ síta, lọ kiri

Ayé kún fún àwọn ọ̀rọ̀ àti àwòrán àti nnkan tí ó yáni lára láti ṣe, fi ọwọ́ kàn wọ́n wo kí o sì yẹ̀ wọ́n wò, láti orí àwọn páálí onjẹ oníwóró àti àwọn pátákó ìgboro títí dé àwọn adágún omi kékeré tí ó ní ẹrọ̀fọ̀ àti àwọn ewé tó ti jábọ́.

Ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ láti ṣe àyẹ̀wò àyíká rẹ.

- Ẹ rìn jáde, kí ẹ sì sọ̀rọ̀ nípa àwọn lẹta, ọ̀rọ̀ àti nọmba tí n bẹ lórí àwọn àkọlé oju-popo àti niwájú awọn ilé ìtajà
- Nígbà tí o bá nra ounjẹ, ṣe àfiwé títóbi, àwọn àwọ̀ àti òórùn àwọn èso àti ewébẹ̀

**Njẹ́ o mọ̀** pé jíjáde láti rìn nṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọmọ rẹ láti kẹ́kọ̀ọ́. Maṣe yára rín ju ìgbésẹ̀ ọmọ rẹ lọ, sọ̀rọ̀ kí o sì fi ọkàn sí àwọn nnkan tí ó bá kíyèsí tabi tí o nbéèrè ibeere nípa rẹ̀.

# Bí a ti nṣe tí a sì nlo àtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ oní kaadi aláwòrán

## Ohun tí o nílò

- Lẹẹdi ìkọ̀wé àti beba fún àtòkọ ohun tí o fẹ́ rà
- Àwọn àwòrán èso àti àwọn ewébẹ
- Sisọọsi ọmọdé tí kò léwu
- Ìlu ihò
- Òwú tàbí ohùn fún síso àwọn àwòrán náà papọ̀

## Ohun tí o maa ṣe

Wá àkọsílẹ̀ èròjà ounjẹ kan kí o sí ṣe àtòkọ kan papọ̀ nípa gígé àwọn àwòrán àwọn èròjà láti ara àwọn ìwé ìléwọ́ àti ìwé àtìgbàdégbà.

Ṣe ìtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ kan nípa lílu ihò sí igun kan lára àwòrán kọ̀ọ̀kan kí o sì fi okùn kan so wọ́n pọ̀.

Jẹ́ kí ọmọ rẹ lo ìtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ náà nígbà tí o bá lọ rajà. Yóò ràn á lọ́wọ́ láti fi àwọn àwòrán náà wá ounjẹ náà. Ẹ jọ sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ẹ rí kí ẹ sì jọ ka iye tí ẹ nílò.

### Àwọn olobó oníràwọ̀

Àwọn àtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ oní kaadi àwòrán jẹ́ ọ̀nà pàtàkì láti bá ọmọ rẹ ṣeré. Gbìyànjú láti ṣe àtẹ̀bọ̀ kọ́kọ́rọ́ ti àwòrán tí o lè rí nígbà tí o bá jáde tí o sì nrìn kiri

### Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life

Nígbà tí o bá jáde tí o sì n rìn kiri pẹlu ọmọ rẹ, fetí sílẹ̀ sí àwọn ohùn tí o lè gbọ́, títí dórí àwọn ariwo ọkọ̀, fère orí ọkọ̀, orin, àwọn ajá tí ó ngbó, àwọn ẹyẹ tí ó nkọrin àti àwọn ọkọ̀ òfúrufú lókè.

Sọ̀rọ̀ nípa ohun tí o gbọ́. Gbìyànjú láti ṣe ẹ̀dà àwọn ohùn náà -- ṣé o lè pa irú ariwo kan náà?



# Níní anfaani sí awọn ìwé

Ilé ìwé, ilé ìkàwé, ibùdó àwọn ọmọdé tàbí jẹ́lé-ó-sinmi agbègbè rẹ lè bá ọ rí ààyè sí àwọn ìwé ọmọdé ọ̀fẹ́. Pè kí o sì béèrè!

Tí wọn bá ṣí gbọ ngan ìkàwé rẹ, o lè tọrọ ìwé lọ́fẹ̀ẹ́!

**Njẹ́ o mọ̀** pé bí o bá ti ní ìwé àwọn ọmọdé sílé sí ni ọmọ rẹ yóò ti ṣe dáradára tó nígbà tí ó bá bẹ̀rẹ̀ ilé-ìwé? Àwọn yìí kò ní láti jẹ́ ìwé tó jẹ́ tìrẹ – kódà, bí ìwé tí a yá bá ti pọ̀ sí ni ó ti dára sí

# Wíwá ìwé kan tí ó tọ́ daadaa

Ó túbọ̀ ṣeéṣe kí ọmọ rẹ túbọ̀ fẹ́ ṣe alábàápín ìwé kan tí ó bá jẹ́ pé òun fúnra rẹ̀ ni ó yàn á. Àwọn ọ̀nà kan tí o lè gbà ràn á lọ́wọ́ láti yan ìwé kan tí yóò gbádùn rẹ̀ nìyí:

- **Yẹ páálí ẹ̀yìn ìwé wò**
  Njẹ́ wọn lè rí awọn ìwé nípa ohun tí wọn nífẹ̀ẹ́ sí bí?
- **Tojú bọ̀ ọ́!**
  Wo inú rẹ̀. Ṣé ó fẹ́ràn àwọn àwòrán náà?
- **Ṣé ó ní àwọn ẹni ìtàn tí ó fẹ́ràn?**
  Ṣé ó fẹ́ràn àwọn ewèlè tàbí ère tàbí àwọn àjèjì tàbí ọkọ̀ ojú irin?
- **Njẹ́ ọ̀kan nínú ẹ̀yin méjèèjì lè pariwo láti bá àwọn àwòrán náà mu?**
  Ariwo àwọn ẹranko, ariwo àwọn ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́, ọkọ̀ ojú irin tàbí rọ́kẹ́ẹ̀tì.
- **Ṣé ìtàn tí ó ní ìṣe ni?**
  Ṣé ó fẹ́ràn láti dara pọ̀ pẹ̀lú irú àwọn ìtàn yìí?
- **Ṣé ìyanu kan n bẹ níbẹ̀?**
  Ṣé wọn fẹ́ràn àwọn ìwé tó ní àwọn àwòrán tí ó nmì tàbí taabu tó n yí? Njẹ́ o lè rí olùṣe tó farasin bí?

**Àwọn olobó oníràwọ̀**

Pa àwọn ìwé ilé ìyáwékà ti ọmọ rẹ mọ́ kí ó lè yàn láti wo ọ̀kan nígbàkúùgbà tí wọ́n bá fẹ́ ṣe bẹ́ẹ̀ Àbí kí ló dé tí o kò pa àwọn ìwé ọmọ rẹ mọ́ pẹ̀lú ohun ìṣeré rẹ̀? Àwọn ère àti ohun ìṣeré ọmọdé fẹ́ràn láti kàwé bákan náà!

**Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life**

Àwọn ìwé àtìgbàdégbà dára láti pín bákan náà. Sọ̀rọ̀ nípa àwọn onírúurú àwòrán náà kí o sì béèrè lọ́wọ́ ọmọ rẹ, èyí tí ó fẹ́ràn jùlọ.



# Gbádùn kíkùn nnkan àti yíyà àwòrán

Kíkùn nnkan àti yíyà àwòrán nran ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti mú kí ìfojúsílẹ̀, ojú ọnà, àti àwọn ìmọ̀ tí yóò nílò fún ìwé kíkọ rẹ̀ dàgbà sókè.

Lo onírúurú ohun èlò tí a fi nsàmì sí ara nnkan—kereyọọnu, lẹẹdi ìkọ̀wé, nnkan ìfárungbọ̀n  tí ó le àti ọ̀dà. Ó jẹ́ ohun ìgbádùn láti lo omi àti irin iṣẹ́ tí a fi nkun nnkan lórí òkúta tí a tẹ́ sílẹ̀.

**Àwọn olobó oníràwọ̀**
Ní ojú ọnà. Ṣe kóríyá fún ọmọ rẹ láti sàmì, ya àwòrán kí o sì fi ọ̀pá ya àwọn àwòrán tí a fi onírúurú nnkan bí ìyẹ́, ìkarahun tàbí ọ̀mùnú-igi.

Gé àwọn ààyò àwòrán láti inú àwọn ìwé àtìgbàdégbà kí ó sì ṣe àwọn àwòrán aláṣàpọ̀.

# Bí o ti lè ṣe ìwé ìránnilétí tìrẹ

**Ohun tí o nílò**

- Ìwé tí a nlẹ àwọn àwòrán mọ́
- Àwọn pẹẹni, kereyọọnu àti lẹẹdi ìkọ̀wé
- Àwọn fọ́tò
- Àwọn ìwé-ìròyìn àtìgbàdégbà àti ìwé àwòrán ọjà
- Sisọọsi ọmọdé tí kò léwu
- Gúluù

**Ohun tí o maa ṣe**

- Ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti ṣe iwájú ìwé ìránnilétí rẹ̀ lọ́ṣọ̀ọ́. Ẹ jọ kọ orúkọ wọn síi.
- Fikún àwọn ọ̀rọ̀ tàbí àwòrán nípa ohun tí wọn yàn láàyò, bí ounjẹ, àwọn ibikan tàbí ohun ìṣeré, tàbí àwọn fọto ìdílé rẹ tàbí àwọn ohun ọ̀sìn rẹ.
- Gba tikẹẹti ọkọ̀ àti àwọn míràn nígbà tí bá jáde kí o sì jẹ́ kí ọmọ rẹ lẹ wọ́n mọ́lẹ̀.
- Gbìyànjú láti jẹ́ kí ọmọ rẹ lọ ohun tí ó ndán, ọ̀dà, àlẹ̀mọ̀ tàbí ohunkóhun láti mú kí ìwé ìrántí rẹ̀ wuni kí ó sì ní onírúurú àwọ̀.

**Iṣẹ́ ṣíṣẹ Words for Life**
Sọ̀rọ̀ nípa àwọn ohun tí ọmọ rẹ fi ọwọ́ yà kí o sì béèrè ohun tí ó ti yà. Ṣa àwọn ìrí àti àwòrán tí a lè dámọ̀ kí o sì fúnra rẹ ya àwọn kan.



# Gbígbáradì fún ilé-ẹ̀kọ́

**O lè múra ọmọ rẹ sílẹ̀ fún ilé-ẹ̀kọ́ nípa:**

- Ṣíṣe àwọn eré tí ó la ṣíṣe àṣegbà àti ṣíṣe alábàápín lọ
- Ṣerànwọ́ fún un láti béèrè ohun tí ó nílò, tí ebi bá npa á, tí òngbẹ bá ngbẹ ẹ́ tàbí ó rẹ̀ ẹ́.
- Kíkọ́ ọ láti wọṣọ fúnra rẹ̀, jẹun fúnra rẹ̀ kí ó sì fúnra rẹ̀ lọ ilé ìgbọ̀nsẹ̀.

**Bíbẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́ lè jẹ́ ìrírí rere fún gbogbo ènìyàn**

- Gẹ́gẹ́ bí òbí, ìwọ ni olùkọ́ àkọ́kọ́ fún ọmọ rẹ.
- Wádìí nípa ilé-ẹ̀kọ́ náà kí o lè lóye ohun tí yóò ṣẹlẹ̀ nígbà tí ọmọ rẹ bá bẹ̀rẹ̀.
- Fi ààyè gba ìbẹ̀wò ilé láti ọ̀dọ̀ olùkọ́ kí ó tó bẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́ tí a bá gbà á wọlé.
- Wo ibùdó-ayelujara fun ilé-ẹ̀kọ́ náà.

Ríi dájú pé o mọ ohun tí ó yẹ láti ṣe ní ọjọ́ àkọ́kọ́: ibi tí ó yẹ láti lọ ní òwúrọ̀, àti ibi tí o ó ti gbé ọmọ rẹ.




**Njẹ́ o mọ̀** pé bí àwọn ọmọdé bá ti nmojú ilé-ẹ̀kọ́ tàbí jẹ́léósinmi wọn tuntun ní ara wọn yóò balẹ̀ níbẹ̀ sí?

## Ka àwọn ìwé nípa bíbẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́

Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ oníruurú ìwé ni ó wà tí o lè ṣe alábàápín nípa ilé-ẹ̀kọ́. Èyí lè ran ọmọ rẹ lọ́wọ́ láti ní ìmọ̀lára ìmúra láti bẹ̀rẹ̀ tàbí padà sí ilé-ẹ̀kọ́.

Àwọn ìwé díẹ̀ ni a ṣe àtòkọ sí ìsàlẹ̀ yìí:

- *Starting School* láti ọwọ́ Janet àti Allen Ahlberg
- *Topsy and Tim Start School* láti ọwọ́ Jean and Gareth Adamson
- *Going to School láti ọwọ́ Anna Civardi* àti Stephen Cartwright
- *Harry and the Dinosaurs Go To School* láti ọwọ́ Ian Whybrow
- *Come to School Too, Blue Kangaroo!* Láti ọwọ́ Emma Chichester Clark
- *I Am Too Absolutely Small For School* láti ọwọ́ Lauren Child

## Ṣíṣe àwọn ètò iṣẹ́ tuntun

Ṣe àwọn ètò iṣẹ́ òwúrọ̀ láti jíjí loju oorun, kí a wọṣọ, àti jíjẹ ounjẹ òwúrọ̀ ‘lákòókò fún ilé-ẹ̀kọ́’ Rí i dájú pé ọmọ rẹ sùn dáradára kí ó sì ṣetán fún ilé-ìwé ní ọjọ́ ákọ́kọ́.

### Àwọn olobó oníràwọ̀

Lópin ọjọ́ náà—kí ọmọ rẹ pẹ̀lú ẹ̀rín kìí sìí ṣe ẹ̀rọ alágbèéká!

### Iṣẹ́ ṣíṣe Words for Life

Ṣe alábàápín ọ̀kan lára àwọn ìwé tí a tokọ náà. Sọ̀rọ̀ nípa ohun tí ọmọ rẹ nrò nípa bíbẹ̀rẹ̀ ilé-ẹ̀kọ́.

National Literacy Trust

Change your story

**T:** 020 7587 1842

**E:** contact@literacytrust.org.uk

**W:** literacytrust.org.uk

Rí wa lórí Facebook: **facebook.com/nationalliteracytrust**

Ẹ tẹ̀lé wa lórí Twitter: **@Literacy_Trust**

Ẹ tẹ̀lé wa lórí Instagram: **@Literacy_Trust**

Ẹ fi orúkọ sílẹ̀ fún àtẹ̀jáde ọ̀fẹ́ wa lorí imeeli: **literacytrust.org.uk/newsletter**

The National Literacy Trust jẹ́ àjọ aláánú tí nọmba rẹ̀ jẹ́ 1116260 àti ilé iṣẹ́ kan lábẹ́ òfin nípasẹ̀ nọmba 5836486 tí a fi orúkọ rẹ̀ sílẹ̀ ní England àti Wales tí ó sì jẹ́ àjọ aláánú tí a fi orúkọ rẹ̀ sílẹ̀ ní Scotland nọmba rẹ̀ jẹ́ SC042944. Adirẹsi wa tó wà ní àkọsílẹ̀: 68 South Lambeth Road, London SW8 1RL.

Patron: HRH The Duchess of Cornwall

© National Literacy Trust 2023. A fún Everyone Ready for School Resource yìí ní àṣẹ lábẹ́ Open Government Licence 3.0.

**Àwọn àtọ́kasí:**

1. https://raisingchildren.net.au/school-age/sleep/understanding-sleep/school-age-sleep
2. https://www.gov.uk/government/publications/uk-physical-activity-guidelines
3. https://www.nhs.uk/live-well/exercise/physical-activity-guidelines-children-under-five-years/
4. Effective Preschool, Primary and Secondary Education (EPPSE). Kathy Sylva et al
5. Social inequalities in cognitive scores at age 16: The role of reading. Alice Sullivan, Matt Brown, 20136.
6. Parent’s perspectives: Children’s use of technology in the Early Years, Dr Susie Formby, National Literacy Trust, 2014